Owo De ! Owo Nigeria

OWO TITUN TILẸ NIGERIA YIO JADE NI ỌJỌ KINI OṢU JULY, 1959.

ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

Akiyesi Pataki

A fiwe yi s e ikede si awọn Aṣoju iwe irohin Eletẹ Ọfe kakiri agbaiye wipe, enkẹn ti ko ba fi owo ti o ti jẹ ransẹ si wa, ao pe lejọ, ako s ni fi iwe irohin ransẹ si ẹnibẹ mọ.

VOL. XI No. 628. LAGOS, SATURDAY, JUNE 13, —JUNE 19, 1959. KỌBỌ MEJI (2d)

# Agbara Ojo Gbe Elede Mefa Lo Ni Abule Oja

ABULE ỌJA. Ojo nla kan rọ ni oru ọjọ Alamisi mọjumọ ọjọ Jimọ ninu oṣu June ọjọ kọkanla si ọjọ kejila, 1959, ni abule Ọja ti o da ijọgbon sile.

A gbọ wipe awon ẹlẹdẹ mefa ni o sọnu ni oru ọjọ yi mọju. A ri ọkan ninu awon ẹlẹdẹ na ti agbara ojo wọ si ẹgbẹ kota kan.

Kini gbe ẹlẹdẹ marun lo o ? ibosi are ? Idi ọrọ yi ni awon ọlopa şi nwa kiri.

Apakan enia sọ pe agbara ojo lo wọ won lọ, awon ẹlomiran si sọ pe bẹkọ, ọlọṣa lo ko won lọ.

## Oba Ilu Adamawa Le Enia Jade Kuro Nilu

YOLA. Nigbati Oloye Awolowo fi lọ bẹ agbegbe Yola wö, Ọkunrin kan ti o jẹ ọmọ ẹgbẹ U.M.B.C. ti orukọ rẹ njẹ Malam Njida fon fere ti won nfi ehin-erin gbẹ fun Oloye Awolowo lati fi yẹsi.



OLOYE AWOLỌWỌ

Lẹhin ti Awolowo lo tan

Ọba ilu Adamawa ti nwon npe ni Lamido ati awon igbimo ranṣẹ pe Malam Njida ti o ngbe Bagala nile Adamawa, wipe ki o jade kuro nilu, ki o si lọ şe atipo si Kafa Gafadi.

Ẹṣẹ ti a gbọ wipe nwon ka si ọkunrin na lọrun ni wipe, o ba ofin atọwọ-dọwọ işedalẹ baba nla won jẹ, ni pa fifun bere elehin-erin fun Oloye Awolowo, eyiti o jẹ wipe a ko gbodo fọn fun ẹnikẹni ayafi Ọba ilẹ Adamawa, on na ni Lamido oba Adamawa tabi Arnado ọba Bagali.

Şugbon Loya ẹgbẹ Action Group kan ti a npe ni Idowu Layi ti tẹsẹ bọ ọrọ na.

## KI LO LE SỌ ỌMỌ DI ỌTA OBI RẸ ?

Olotu,

Jowo gba mi laye lati bere gbolohun oro yi lodo awon ọjọgbon ninu awon okawe rẹ boya won le fi ye mi.

Oju mi ti ri ọmọkunrin kan ti ko fẹran iya rẹ. Bi iya na ba fọwọ kan ikoko ọbẹ fifọ ni ọmọ na yio fọ ikoko ọbẹ na.

Bi iya na ba fọwọ kan owo, bi ebi yio ba pa ọmọ na ku, yio ya pa a ku ni, ko jẹ fọwọ kan owo na mo.

Ọmọ ti ọkunrin na bi, iya rẹ gbe ọmọ na o mba şere, bẹni ọmọ na kọsẹ ba ọmọ rẹ lọwọ iya re, o kọ ọmọ na silẹ patapata.

Owe awon Yoruba kan sọ bayi wipe, "Enia bi iya ko si, Tani le şe bi baba ẹni fun ni" Owe miran tun sọ pe Iya ni wura, Baba ni jigin.

Ẹnyin ọkawe wa, bawo lati rin ti omo eni şe di ọta ẹni ba yi ? Ẹ la mi loye rẹ.

J. Kerẹkẹndu

## Ololajulo Omo'ba Goke Agba



LONDON. A gbọ irohin wipe Dokita Billy Graham ọmọ ogoji ọdun, ajihinrere ara ilu Amerika pẹlu iyawo rẹ fi omi gbigbona tun ẹnu şe, ninu Gbọngan Afin nla ile Alaiyeluwa Ọba ilu Oyiebo pẹlu Ọba Obinrin ati Ọlọlajulọ ọkọ rẹ ni alẹ ọjọ Alaruba ọjọ kọkanla oşu yi.

Ọjọ na si jẹ ọjọ pataki fun awọn Alaiyeluwa pẹlu nitoripe o bo si ajodun Keji-din-logoji ojo ibi Ọlolajulo omo'ba Duke of Edinburgh.

Aşeyi ş'amodun o, K'ọba ki o pẹ.

## Oku Ọlomo Gege Lao Gbe

ABẸOKUTA., "Erin wo loke amilala" ni ọjọ Alamisi ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu June, 1959 ni Agbole Bohunku, ni Agọ-Odo, nigbati Oloye Joseph Jọlaoṣo Ṣogbọla mi emi ikẹhin rẹ. Ologbe yi ni baba fun Ọgbẹni S. Ọla. Ṣogbọla, oṣiṣẹ ti No 29, Moloney Street, Ẹko, o fi ilẹ bora nigbati o d'agba di ẹni ọgọrin ọdun laiye.

Ki a sọ mba ṣoki, a bi Ologbe Oloye Joseph yi nilu Abẹokuta ninu ọdun 1879, ọmọ bibi inu Ologbe Oloye Ṣhogbọla, Lisa ti Odo nilu Abẹokuta ni iṣe.

A ṣe isin isinku rẹ ni ọjọ keji ninu Ṣọṣi Holy Trinity, ni Ikereku, Alufa Ṣọṣi na si ṣe iwasu ti o wu enia lori nipa igbesi aiye Ologbe na, gẹgẹbi o ti jẹ Onigbagbọ ododo, alanu ati oninu're si gbogbo enia.

Lẹhin isin ikẹhin ni Ṣọṣi ni awọn ọlọpa Onifere ti ijọba ibilẹ ati awọn ẹgbẹ akọrin, t'ẹbi-t'ọrẹ pẹlu ojulumọ ati awọn olubanikẹdun to tẹle oku rẹ lẹhin rin irin ibusọ meji lọ si itẹ-oku ni Ibẹrẹkodo lọ rẹ eṣikusilẹ-korofo-ara-oku Oloye Joseph tẹ sinu iboji rẹ.

Ki Oluwa f'ọrun kẹ.

---

## Iwe Si Salamotu Aniwura

Sala Aniwura,

Mo ki ọ pupọ, ṣe daradara lẹ wa, gegebi emi na ti wa loni. Akọkọ ninu ọrọ mi siọ nipe nigbati mo ri ọrọ rẹ ti o so sinu Eleti-Ọfẹ inu mi dun si nitori ọkanna ni ẹsin awa mejeji. Emi ti mo kowe yi koiti ni iyawo rara, obinrin ti o jẹ Musulumi ododo ni mo nwa Ṣugbon nigbati mo wa gbo oro ẹnu rẹ o jẹki inu mi dun. Bi o ba lẹ gba lati fẹ mi inu mi yio dun. Bi o ba le gba ifẹ fun mi.

Emi na ngbero lati lọ si Mẹka ni odun ti o mbọ.

Mo nreti esi rẹ
Alufa Yisa Eko.

## JAGUNJAGUN KAN KU IKU JAMBA LỌNA AKURẸ

AKURẸ Lieut John Onu Aguloṣi ti iṣe ọkan ninu awọn ọga ọmọ ogun ilẹ Nigeria, ti o kuro nilu Enugu ti o si mbọ wa gba ipo A.D.C nilu Eko. Nigbati mọto rẹ kuro nilu Akurẹ ti o nlọ si Ilesha, ni ọgangan busọ marundiladọfa, ibẹ ni mọto tirẹ ti Sọlu mọto miran, a si gbọ wipe loju kanna nibẹ ni ọga awọn ọmọ ogun na ku si.

A gbọ wipe on lo mbọ wa gba ipo Aide de Camp fun Gomina agba ni Eko.

Nilu Ibadan ni awọn sinku re si pelu eye ti awọn ologun ma nṣe fun isinku ti wọn. Sun re.

---

## Iwe Si Salamotu Aniwura

Olotu,

Jọwọ gba mi laye lati ja iwe kekere yi ranṣẹ si Iyafin Salamọtu Aniwura. Lẹhin ọpọlọpọ kiki mi si ọ, ṣe alafia ni ẹ wa, gẹgẹbi mo ti wa nihin.

Mo ri ka ninu iwe irohin ti ọjọ kẹfa, inu mi si dun lati sọ fun ọ pe mo dagba di ẹni ọdun mọkanlelogun nko ni iyawo rara mo si ni mimọ nipa ẹsin Musulumi diẹ.

Ọmọ orukan ni emi se, mo ni Baba ṣugbọn nko ni iya mo si jẹ ọmọ ilu Ilọrin iṣẹ alufa ni nwọn ṣe ninu ile wa. Mo ka iwe ti oloyinbo mẹrin. Owo şiṣe ni iṣẹ temi pa npa, mo mba mọto lọ si Ṣokoto, Gusau, Bidda,

Emi yio kapa ọkanj wa mi nko ni fẹ iyọlẹnu ko si owo lọwọ mi Inu mi yio dun bi mo bari esi iwe yi gba.

Emi ni
Mallam Musa Amuda.

---

## E MA KA IWE IROHIN ELETI-OFE

# Enia Dudu Di Olugbimo Nilu Oyinbo



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Ọgbẹni Stephen Ojoku ara ilẹ Uganda ti o lọ kọ iṣẹ Dokita nilu Oyinbo ṣugbọn o di ọkan ninu awọn Olugbimọ ninu igbimọ ilu Oyinbo.

Ọgbẹni S. Ojoku jẹ ọmọ ijoye ilu kan ti nwọn npe ni Lango ni agbegbe ilẹ Uganda.

Iṣẹ Dọkita lo wa kọ nilu Oyinbo, o si bẹrẹ iṣẹ Nurse, ṣugbọn nigbati o ṣe, ọrọ ilu bẹrẹ si jẹ ẹ lọkan, kẹrẹkẹrẹ bẹ, nwọn dibo fun, o si wọle ninu igbimọ.

## ẸKỌ KINI NI EDE HAUSA

O yẹ ki Abẹrẹ Ẹkọ yi pẹlu iṣiro ati awọn oruko Orike-rike Ara. Dajudaju ti aba fi eyi bẹrẹ yio tete fun wa ni ilọsiwaju nipa kikọ ede yi.

Daya Eni, Biyu Eji, Uku Ẹta, Fudu Ẹrin, Biyar Arun, Shida Ẹfa, Bokoi Eje, Tọkọs Ẹjọ, Tara Ẹsan, Goma Ẹwa.

Kayl Ori, Gashin-kayi Irun-ori, Gochi Iwaju, Kẹya Ipakọ, Ido Oju iriran, Fuska Ereju, Anchi Imu, Baki Ẹnu, Kunni Eti, Akori Ehin.




## LAGOS RACE CLUB

A General Meeting will be held in Saint George's Hall on Monday, July 6, 1959 at 6 p.m. Only members of the club will be admitted and Membership Badges will be inspected at the door of the Committee Room.

AGENDA : 1. Chairman's Address
2. Accounts
3. Election of Chairman
4. Election of Committee Members.

RULE 11 — "The Management of the Club shall be vested in a Committee of 18 in addition to the Chairman who shall be elected annually. Provided that no one shall be eligible for election at a General Meeting as a member of the Committee unless his name duly proposed, and seconded, has been handed to the Secretary at least 14 clear days before the General Meeting in question and the list of such nominations shall be available for inspection at the Secretary's Office seven days before the meeting x x x x".

RULE 12 — "x x x Any Full Member wishing to move any resolution at any Annual General Meeting shall give notice in writing to the Secretary at least three days before the Meeting.

## ELETI - OFE D'ARABA

## Oba Olofa Sa Asala Silu Ibadan

Alaiyeluwa Wuraọla Isioye, ti o jẹ oye Ọlọfa ilu Ọffa, ni Ọba Ilọrin yọ kuro lori oye, fun ẹsun wipe Ọlọfa ti dagba to ẹniti o le gba isimi kuro lori oye ọba. Ki ise ipa to de lati fi mu ọba na kuro lori oye, o ti salọ si ilu Ibadan.

Nigbati Ajẹlẹ kekere ti Ilọrin de lati wa fi Mustafa Keji han awọn igbimọ wipe dipo Wuraọla Isioye Mustafa yi ni ẹniti Ijọba Ilọrin yan si ori oye ọba Ọlọfa, nwọn si ti we lawani oye fun nilu Ilọrin. Nigbati awọn igbimọ gbọ wipe Mustafa ni nwọn tan fi j'oye, gbogbo wọn si binu jade.

Ọgbẹni J. S. Ọlawọyin sọ wipe, ọtọ ni ọrọ ti nwọn fi sinu iwe wipe nwọn fẹ sọ nitorina, awọn ko le gba Ajẹlẹ l'oye lati ba won soro nuran ti o yato, nigbogbo awon igbimọ ba binu jade, nwon si tuka.

### JAMBA ṢẸLẸ NINU ỌKỌ KAN

Ninu ọkọ kan ti o nko epo mọto kiri ti o si jẹ ti ijọba ilẹ Kurumọ, lo gbona, ti o si fọ lojiji ni agbami okun rere ni ilu Durban ni apa isalẹ ilẹ erekuṣu Africa.

Ninu jamba na, awọn enia marun lo fi ara gbalamọ. Enia dudu mẹta Mulato kan ati Oyinbo kan ọkọ na si jona si aria omi awọn enia marun lo ku.

### Afese Pa Meje Apa iv

Lẹhin ti Afẹsẹ pa meje ti sun tan laimo pe leti ilu kan ni on sun si, ijoye ti o kọkọ ri leti ilu won sare lọ rohin fun Ọba o wipe, Kabiyesi ! mo ma ri Ọkunrin ti nwon npe ni Afẹsẹ pa meje nisisiyi ! Ọbadide giri lori itẹ rẹ, o wipe, ni bo ni o gbe ti ri ?

Ijoye na dahun pe, o mbẹ lọhun ni e sun. Ni kiakia, Ọba ranṣẹ pe awon igbimọ rẹ, o si fi ọrọ na siwaju won, nwon ṣe ipinnu nwon si fi idi ọrọ mulẹ.

Awon ijoye ilu wa ko ara won jọ' nwon pe onilu, nwon nlu, nwon njo, nwon nlọ pade Afẹsẹ pa meje. Bi ariwo ijo ati ilu na ti pọ to ko le ji Ọkunrin na.

Nigbati afẹsẹ pa meje ji o na tantan, o wipe Omiran wo lo npariwo bayi ? Awon enia si sunmọ, nwon sọ fun pe, nigbati a gburo rẹ pe o mbọ, ọba ba wipe ki a wa pade re. Ibẹ ni o ti tẹle won lọ.

Nigbati o ri i, rẹ dun, o w fun u pe mo ti gbọ irohin rẹ.i mo si ti nifẹ lati ri ọ lati wa gba mi lọwọ awon nkan mẹta ti o nyọ awon enia mi lenu. Bi o ba le gba mi kuro lọwọ awon nkan mẹtẹta nwonyi, ngo fi ọmọ mi obinrin fun ọ ni iyawo.

Nigbati Ọba ti ṣeleri ọmọ rẹ Obinrin fun Afẹsẹ pa meje tan o bu ramuramu o wipe emi ! emi !! emi ni ofẹsẹ-mejeji so kondo, ọbara-mba-kunmọ. apa mi ọtun yi gba igba kumọ, esẹ mi osi le tẹ igba omiran pa, ẹni ti a nle bọ, ti o nle ara iwaju, emi Afẹsẹ-kan-pa-meje. Ki o to ki ara rẹ ni oruko yi dele, ati ọba ati gbogbo enia ti tuka.

Afẹsẹ pa meje pe ni bo ni awon Omiran mẹta na wa ti o nfi igba gbogbo wa ko awon ara ilu peju ? Ọba si nọ ika owọ rẹ, nwon mbẹ lọhun ni

Ọba lo ko ibon ati ẹtu wa, Afẹsẹ pa meje dahun pe, ojo enia l'o 'nlo ibon ati etu, ẹ lọ ba mi wa okuta meta wa,ki eyi ti o kerejulọ ninu awon okuta na tobi to ori enia.

Eyiti o kere ninu won to ori enia, ekeji tobi to iṣa omi, ẹkẹta to iko o aro. Afẹsẹ pa meje ni on lẹ ki ọba fun on ni ṣọja mejila, nigbati awon ṣoja ntadi mo ẹhin o bere gbe awon okuta na funra re, o si jade lọ. Ẹma ka iwe irohin Eleti-Ọfẹ, lọse ti o mbọ co gbọ bi o ti ṣe iṣẹ na si.

### EBUN OWO ẸGBẸTA LA-DIN ỌGỌRUN PỌUN

LONDON. Iwe irohin olokiki kan nilu Oyinbo ti nwon npe ni "The News of the World" ni a gbọ wipe o ṣe ikede ẹbun ẹgbẹtala-din-ọgọrun poun (£2,500) ni sisan fun eniti o ba le fi ona ti owo ọlọpa le fi tẹ ẹniti o gun Ọgbẹni Kelso Cochrene, ara ilu West Indies lọbẹ pa laipẹ yi han, ni agbegbe Notting Hill nilu London.

Nwon yio fi ẹbun owo na fun ẹniti Olotu Iwe irohin na ba ni itẹlọrun pe, on l'ofi ọna ti owo fi tọ odaran na han ti nwon si ṣe idajo apania le lori.

Eni to ba mọ nipa re ki o so,

ELETI - OFE
A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'EJỌ
EDITORIAL OFFICE & WORKS 28, Kosoko Street, Lagos. CABLES & TELEGRAM "ELETI - ỌFẸ LAGOS"
P. O Box 467 Phone 23370
VOL. XI. NO. 628. SATURDAY JUNE 13 - JUNE 19, 1959

# Ejo Ti Ku, Owere L'o Nja

Gbolohun akọle oke wosika wa ọsẹ yi ni o jade l'ẹnu wa nigbati a nka aroye ti ko mọyan lori ti awọn enia nṣe lẹhin ti Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, Olotu ijọba Iwọ-Orun ati akonijẹ ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ṣe ikede jade fun gbogbo enia, iṣẹ ti ẹgbẹ Afẹnifẹre yio ṣe fun anfani ilẹ Nigeria bi a ba fi ibo wa yan wọn ti a si gbe agbara ijọba apapọṣe le wọn lọwọ.

Gbogbo iṣẹ ti Oloye Awolọwọ sọ wipe ijọba Afẹnifẹre yio ṣe ti nwọn ba bori ninu igbimọ apapọṣe ti wọn aladakandeke npariwo le lori ni ijọba Iwọ-Orun ti nṣe ni ipinlẹ Iwọ-Orun ayafi iwọn iba ti o jẹ wipe ko si ni agbara adaṣe ijọba ipinlẹ kan bikoṣe ijọba apapọṣe, eyini ni ti owo anu fun awọn enia ti ko ri iṣẹ ṣe, ati itọju awọn afọju enia, dida agbegbe keke-ke sile ati bẹbẹ lọ.

Lẹhin irufẹ awọn ti a ka silẹ wọnyi, gbogbo iṣẹ yoku bi ẹkọ ọlọfẹ fun awọn ọmọ ilewe, itọju fun awọn ti ko ju ọmọ ọdun mejidinlogun lọ ni 'ile Iwosan lọfẹ, owo ṣile marun ojumọ fun awọn oṣiṣẹ ati owo ifẹhinti fun awọn oniṣẹ ojumọ ti o ba ṣiṣẹ rẹ daradara fun ọdun meji tabi jubẹlọ, gbogbo anfani ti a ka silẹ wọnyi ni ijọba Action Group ni ipinlẹ Iwọ-Orun ti nṣe fun awọn enia.

Bi a ba ri wipe ojulowo ọrọ ni Oloye Awolọwọ sọ ninu koko mẹrinla ikede rẹ, ohun ti o yẹ ni ki gbogbo wa gbaruku ti lẹhin ki a si dibo fun ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ki amaṣe iregbe ti ko nilari mọ.




# Oloye Akintola Tun Ileri Re Se.



ZUNGERU. Nigbati nwọn nṣi ile iṣẹ Post Office ti nwọn fi £3,700 kọ nilu Zungeru, Oloye Akintọla sọ wipe, on ti pinnu lati sa gbogbo agbara on wipe ki o maṣe si idiwọ fun iṣẹ ati owo lati wọle.

O sọ wipe gẹgẹbi on ko ti ri aye lati wa sibi iṣile na, ọkan on mbẹ pẹlu wọn ninu ohunkohun ti nwọn ba ṣe.

Laipe jọjọ ao ṣi ile iṣẹ Post Office titun meji si ilu Bama ati Zoru ni agbegbe Ariwa ilẹ Kamarun.

# Egbe N.C.N.C. Gba Kola Balogun Pada



Oloye Kọla Balogun ti o jẹ ọkan ninu ọmọ ẹgbẹ Asikiwe, (N.C.N.C.) ti o si wa ninu awọn ti o ṣe ọtẹ si aṣiwaju wọn Asikiwe wipe ayafi ki o fi ipo re silẹ gẹgẹbi aṣiwaju ki ẹlomiran tun dan ibẹ wo.

Nitori idi eyi ni nwọn sa yọ kuro ni ẹgbẹ N.C.N.C. ti on pẹlu awọn to dite na fi lọ da ẹgbẹ Dẹmọ silẹ.

Ṣugbọn ti a ko mọ bi‿ọrọ na ti tun jẹ'ki o to fi ẹgbẹ Dẹmọ silẹ. Ọrọ na wa dabi owe Ọmọ Oninakuna.

Igbimo N.C.N.C. da oro rẹ ro, nwon si tun gba a pada sinu ẹgbẹ N.C.N.C.

# A Fi Fila Pa Ekun Ojo Kan Ni Iyi Re Mo

Ijoye kan wa nilu Ondo ti nwon npe ni Ojọmu, o ni fila kan ti o ma nde nigbati o ba nlo si ogun. Nigbati o ba pada de y'o fi fila na ko sile. Gbogbo enia ti o ba wọ inu ile, ni yio ri fila na lori iko.

Awon omo ijoye yi, a ma bere lowo baba wọn wipe iṣẹ wo ni fila ẹtu yi ṣe? Baba won a si ma dawon lohun wipe Ha! ẹnyin omo mi ẹyin ko mo pe a fi fila pa ẹkun ojo kan ṣoṣo ni iyi rẹ mo Nigba gbogbo ni baba yi ma nso irufẹ oro bayi fun awon omọ rẹ nigbati o ṣe Ọjomu ṣalaisi.

Gbogbo oriṣi awon egbogi ti o mbẹ ninu ile ni Olegbe Ọjomu na ṣe itunmo rẹ fun awon omo re ṣugbon ko ṣe itumo fila na fun won titi o fi ku.

Akọbi ọmọ ijoye Ojomu wa lọ si odọ ọkunrin agbẹ kan ti o jẹ ẹgbe kanna pẹlu baba rẹ, o soro ẹdun okan re nipa fila ti baba won ko se itumo re fun won ki o to ku.

Ọkunrin agbe na dahun pe Ha! o mase, asise nla n i baba re se. Ohun ti emi ri ti mo si mo ni wipe baba re nlọ fila na bayi loju mi nigbata mbẹ ni ibudoogun lojiji ekun kan yo si ibudo ogun, ekun na je ako kosisi eni ti o leba ekun na koju a ya fi Baba re ti o si fila ori re ti o si jan a mọlẹ ni iwaju ekun na. Ekun na s i f o soke, o f i ori sole, o na tantan,o si ku.

Nigbana ni omo ijoye na wipe tabi nitori fila yi ni, baba won se ma nso bayi pe, afi fila pa ekun lojo kan ni iyi re mo. Odupe lodo baba agbe na o si jade lo.

(Koiti Pari)

# Enia Dudu Nsise Ni Afin Oba



Eniti a nwo lowo otun ti o fẹ koja niwaju Soja ti o nṣo ẹnu-ona oba ilu Gẹsi, ni Ọgbẹni J. B. Ọduntan, on ni enia dudu ti ijoba Gẹsi koko yan lati ma gbe inu afin Ọba ki o si se irohin ohun ti o nlo ninu ile oba.

Ọgbeni Ọduntan ko iwe nile ẹko Oxford, Oniwe Irohin ti Ijoba Ghana lo ti nṣe ri ki o to lo bẹrẹ iṣẹ nilu Oyinbo, ninu ile Ọba.



AVAILABLE AT:-
AKOSHILE BROTHERS
5, BALOGUN STREET WEST.
P.O. BOX 599. LAGOS.

## IJỌBA IWỌ-ORUN PE-GEDE!

IBADAN. Irohin ti a ri gbọ lati ilu Ibadan ni wipe Oloye Anthony Enahoro ti iṣe Olotu Ẹtọ-ilu ninu ijọba ipinlẹ Iwọ-orun ti pari iwe adehun iṣẹ "Ẹrọ ti yio ma sọrọ ti ao si m a w o aworan ẹnito nsọrọ na ninu rẹ" (Television) pẹlu awon onise Ẹrọ gbohungbohun ti ilu Oyinbo. Nwon si ti ki ọwọ bọ iwe na, o jẹ adehun ti iṣe ọdun mẹdo-gun.

Nwon so wipe ibi meji ni yio jẹ ibujoko ẹrọ na, okan ni ilu Ibadan ati ekeji ni ilu Abafon nitosi Eko. Ẹrọ na y'o bẹrẹ iṣẹ ninu oṣu August, sugbon iṣẹ rẹ ni toni-pẹrẹwu yio tẹrẹ to ipari odun yi.

Nwon ti bere iṣẹ kiko ile iṣẹ Ẹro na nilu Ibadan ninu osẹ yi.

## ILU AMERIKA KỌ IYA NIA SỌTỌ

LITTLE ROCK — Ni ilu kan ni agbegbe ilu America ti a npe ni Little Rock, Arkansas, ninu ọdun to kọja ni a gbọ wipe awon ara ilu na kọ ọmọ enia dudu ninu ile'we ti ọmo enia funfun ti nkọ ẹko, ti Gomina ibẹ si f'aramọ, laibikita fun ofin ti Alaṣẹ ijọba Amerika se wipe enikeni ko gbodo se iyasọto nitori awo enia. Lasiko na, awon enia atata ba Gomina na wijọ nitori iwa yi ṣugbon ko gba ti won.

Laipẹ yi ni agbọ wipe asiko ati tun dibo yan awon Olotu ilewe na to, awon enia meta ti ko faramọ iyasọtọ ni nwon dibo fun, ti nwon si yo awon ayani-sọtọ kuro ninu igbimọ Olotu ile ẹkọ na.

Nipa bẹ, a ni ireti wipe awon ilewe bi merin ti won ti titori ọrọ na ti yio di ṣiṣi pada nisisi-yi ti ilu fi han wipe awon ko gba iwa iyasọtọ larin enia sira-won.

## ENIA ṢORO Ẹ MAṢE FI ENIA ṢERE

Enia ṣoro, ẹ maṣe fi enia ṣere, bo ṣe olowo ni, bi ta-laka ni, enia ṣoro ẹ maṣe fi enia ṣere. Nitori enia ko ṣe finu han bi o ba ni ọgbọn fi si ikun ara rẹ. Gbogbo awon enia lo di eke aiye di aiye agunla.

2. Aribanijẹ' ani n w ọ n aribanijẹ, kole mu ti ọwọ rẹ wa Aribanijẹ agbọn isalẹ, bi enia ku ni owuro yio ya ni alẹ ba! iwọ orẹ mi, enia ṣoro ẹ maṣe fi enia ṣere.

3 Owo yẹ ile, osi yẹ ode oṣi ko yẹ ọmọ enia oṣi lo nje tani mọ ọ ri, owo lo njẹ mo ba ọ tan, en'a ṣoro, ẹ maṣe fenia ṣere.

4. Oju lari ni a nṣododo Asẹhin deni ko wọpọ. Ṣaṣa, enia lo ofẹ ni lẹhin bi ako si nile, ṣugbọn ati aja ati ẹran lo nfẹni lojo ẹni. Ẹnu Ẹnu wọn lofa, ẹnu wọn loje eke ni ọmọ araiye. Nitorina enia ṣoro.

5. Otoṣi to mba Ọlọrọ rin ako oju lo nya. Ọrẹ ki iwọ da ọbẹ ki emi yan ẹkọ lo wọpọ laiye Bi a ko ku, iṣe ko ni tan, bi o pẹ titi aojẹ ẹran to terin.

6. Ẹniti a ni ko kini lehin fi ẹgun sọwọ ẹniti a pe ko lẹni loju fi a t a s i ẹ n u, ẹniti a ni ki a fẹhin ti k a mu didun ọsan gainga in lo nfun ni mu

## JAMBA SELẸ LOKO IGI GEDU

IJEBU-ODE Agbọ irohin wipe awọn enia met a jade lo bẹ igi gedu, bi nwọn ti t i nge igi na lowo nigbati o ma wo, o wolu igi miran, eyiti, o se iku pa ọkan ninu awon enia na, ti o si se eni keji lese. Ọ r u k ọ awon enia meta na niwonyi, Irasmus Igbope, ni igi wo lu molẹ ti o si pa bamu-bamu.

Ẹni keji ni Enokun Igbope on ni ẹni ti o fi ara ṣeṣe ti o si wa ninu roju jẹ ati roju mu ni Ile Iwosan.

Mission Botu ti o jẹ a g b nikan soso lọ bọwa sile w a jihin.

Ki Ọlọrun sọ wa ki a maṣe rin lojọ ti ebi npa ọna.

## ỌDARAN BU S' EKUN NI KOTU

EKO. Ọdọmọkunrin kan ti o nje Robert Akerele ti o nṣe iṣe lebira, ni awọn ọlọpa ka mo, ni biti o gbe nmu ewe t a b a buruku kan t i nwọn npe ni Igbo.

Ọkunrin na jẹwọ wipe nitoto ni on mu ewe taba I g b o na ṣugbọn on ko mọ pe, nwọn ko gbodo mu nitori alejo ni on je nileyi.

Adajo sọ fun wipe ki o lo san poun mejila tabi ẹwọn osu meji. Ibẹ ni ọkunrin na ba kun le ti o nsọkun, ti o nrawo-rase adajọ ni dandan ti ofin lo ni lati se

## Awọn Olopa Wa Oba Olofa Ni Awati

ỌFFA. Alaiyelawa Ọba Wuraọla Isioye Olọfa ilu Ọffa ni ijọba ilẹ Hausa se iwe wipe, ki awọn ọlọpa lọ ki mọlẹ ninu afin rẹ ki nwọn si wa a lọ si Lọkọja.

A gbọ wipe nigbati awọn ti o mu iwe ipa na de nwọn ngbọ ohun Olọfa ti o nsọrọ ninu afin rẹ sugbọn awati ni nwọn fi se.

Lẹhin ti awọn wa Ọlọfa ni awati, awọn ọlọpa ko awọn idile mẹrin ti o nfi ọba jẹ, awọn ni Esa, Ojomu Sao, ati Balogun, nwọn si ko gbogbo wọn lọ si Ilọrin nwọn si fi Ọgbẹni Mustafa Keji joye ọba Ilọrin si we lawani fun.

Balogun ti o jẹ ọkan ninu awọn afọbaje tako ọba ilọrin wipe bayi kọ ni a se njẹ oye ọba ni Ọffa, o lodi si aṣa ibilẹ, awọn emẹwa ọba Ilọrin ni ki o dakẹ nibẹ.

Ijọba ilẹ Hausa sọ wipe, awọn da ọba Ọlọfa duro lori oye nitoripe agba ti de si, ijọba ilẹ Hausa ti nfa ọrọ yi mọ awọn ara ilu Ọffa lọwọ lati ọjọ 16th osu February 1957, ti awọn ara ilu Ọffa sọ pe bi ọba kan ko ku ọba kan ko jẹ.

---

## Oye Oba Ye Lori Ifemenam

Ẹniti a npe ni Ifemenam yi ni ọmọba ilu Nando ti o tan irohin kalẹ nijọsi wipe, awọn enia kan npete pero lati pa Dr. Nnamdi Azikiwe eyiti o da rogbodiyan silẹ larin ilu ti o si fẹ fi ori awọn agbagba meji gba ara wọn.

Nigbati aye lati jẹ ọba Nnado si silẹ awọn enia rẹ taku wipe nwọn ko le yan a ni ọba. Ẹniti a gbọ wipe nwọn fi jẹ ọba na ni Ifeachor Egbo.

Nigbati nwọn fẹ joye na nwọn lọ ko awọn ọlọpa wa lati Onitsha lati dabo bo won nitoripe oye yi ni Mofunnaya Ifemenam ti npekiki lati jẹ. Nitoripe ninu ọdun ti a wa na lo sọ pe oun ni ọba (Ẹze) ilu Nando.

---

## IWADI LORI IKU ỌREMULE

IBADAN. Ọgbẹni Ologbe Ọrẹmule ti o ti nse isẹ akọwe kotu ilu Ibadan ti o salasi lọjọ aipẹ yi ni a gbọ pe awọn Dokita jẹrin nipa rẹ wipe, ọti amupara lo se iku pa ologbe na.

Ṣugbọn nigbati iyawo rẹ, Iyafin Christiana Ọrẹmulẹ nsọro niwaju adajọ ti o nse iwadi oro na o wipe on ko ri oti ti lẹnu ọkọ oun. Na ale ọjọ kedogun osu May ti ọdunni ni on ri ọkọ on ti o nsa gira-gira bọ lati ode kan ti o ti lọ, o si nkigbe igba aiya rẹ mi o si nla-agun wọwọ.

On kigbe lo ba awọn ara ile fun itanlẹwọ lẹhinna ni awọn gbe lo si ile Alaisan ki o to ku sibẹ lọjọ keji. Adajọ na si sọ wipe akọkọ ti Ọlọrun l'o to ni awọn ba pari oro na sibẹ.

---

## ỌLỌPA WA ỌDARAN KAN PADA SILU RE

Ọkunrin kan Momodu Zaria ti ko nisẹ meji ti o nse, a yafi ki o ma fo ile kakiri l'o lọ fọ ile Adamu Katsina ni awọn ọlọpa ba ramu nwọn si ju si ẹwọn osu mẹfa.

Awọn Ọlọpa sọ pe, oniibara wọn ni Momodu Zaria, ni nwọn ba tile ju si ẹwọn ko ni le fi iwa rẹ silẹ ayafi ki ijọba wa a pada lo silu rẹ lẹhin ti o ba pari ẹwon rẹ tan a gbo wipe ijọba ylo wa a pada lo silu rẹ.

---

Kere o !

A ni orisirisi ogun German to sẹsẹ de, fun onirunu aisan tọkunrin obinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS MEDICINE STORES
7 Egerton Road Lagos

---

# Dr. Mbadiwe Pe Azikiwe Ati Benson Lejo


DR. K O. MBADIWE


DR. 'NNAMDI AZIKIWE

Irohin kan wa wipe Dr Mbadiwe pe Lọya Benson, Asikiwe ati Iwe irohin Pilot lejọ si kotu fun esun wipe nwon ba on ni orukọ jẹ, ki adajọba on gba ọkẹ marun poun lọwọ won.


LỌYA T.O.S. BENSON

Adajo ni ki Dr Mbadiwe lọ rojọ tirẹ sinu iwe, ki Lọya Benson ati Pilot sẹ bẹ gẹgẹ ki nwọn fi ransẹ lẹhin osu kan.

## OKU ENIA DI OKU EWURE

BENIN. Irohin kan wipe, awọn ọlọpa gbe oku kan ti a di sanu asọ funfun wa sile alaisan fun ayewo lati mọ kini sababi ohun ti o se iku pa ọkunrin na.

Agbọ pe nigbati Dokita de ibe lati ye ara oku na wo, o si asọ kuro loju rẹ, iyalẹnu lo jẹ fun Dokita na lati ba ewure nibe, kini a ti npe eyi si?. Ọrọ na ru awọn ọlọpa loju.

## TANI GBE KO LO BE?

EKO. Ọdọmọbinrin kekere kan, bere si gbẹ ara sanle, o nkigbe pe „Mo ku o,, mo daran „Mo ri ogun".

Ayiluka Eleti-Ọfe bi i bere wipe, kini ohun ti o de si o.?

Ọmọbinrin na dahun wipe nwọn gbe ko lo be mi lo, nigbati mo lọ sewo lati fun eni kan ti o ba mi ra ọka kọbọ .Bayi ni nwọn gbe kọlọbẹ lọ bambam.

Fun anfani ẹnyin onkawe wa ti ko mọ ohun ti nwọn npe ni kọlọbẹ ọka gari riro ti nwọn nta kakiri ilu Eko laisi ọbẹ ni nwọn npe ni ko lo be.

Eni ti o ba ni obe nile sugbon ti ko ba le se wahala ati ro oka awọn lo nra ọka ko lẹ bẹ.

## ENIA MEJI KU S' ONA LAI DE ORI OKE

INDIA. Oke kan wa nilẹ India ti nwon npe ni Himalayas Oke yi jẹ eyiti o ga pupo lara rẹ ni orisirisi awon okẹ nlanla wa.

Ọkan ninu awon oke na ni Ama Dablan, giga oke ti a wi yi to ẹsẹ 22,300 lo si oju sanma.

Awon agun-oke meji (climbers) dide lati ilu Gẹsi lati lo gun oke yi titi de sonso ori rẹ. Oruko won ni Ọgbẹni G. Fraser ati J Harris. A gbo wipe ko si oke ti awon mejeji yi ko le gun.

A gbo pe jamba sẹlẹ si awon mejeji ninu osu May jamba na lo si pa awon mejeji. Nibiti nwon ti ngun oke na ni won ku si.




## Alabojuto Ile Ijoba ati agbegbe Ilu Ibini



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Anthony Enahoro, ti ise Alabojuto ile ijọba ati agbegbe ilu Ibini (Minister of Home and Midwest Affairs), on ni ẹniti o ba wọn se iwe adehun ise erọ Tẹlifisọnu fun ipinlẹ Iwọ-Orun a se alaye rẹ si oju ewe kẹrun iwe wa ọsẹ yi.

## ỌLỌFFA TITUN DUPẸ LỌWỌ IJỌBA ILẸ HAUSA

OFFA. Ọlọfa titun ti o sẹsẹ je sọ wipe on ko ni gbẹsan lara ẹnikẹni nilu Ọffa fun ohun ti nwon ti se fun on, bi o ba kanran eyini, ilọsiwaju ilu Ọffa ni on yio ma wa. O ni on tile dupẹ lọwọ Ọlọrun ti o jẹki ogun awon baba nla on tun pada si ọdọ on. Nitoripe itan ti on ni ẹniti o kọkọ jẹ oye Ọlọfa kini Orukọ rẹ ni Ọba Olugbense.

Ọba titun na sẹleri wipe ọba ti on jẹ yi, on ko ni se ojusaju ẹnikan, on ko si ni fi ikanra gbẹsan lara ẹnikẹni. Nigbati gbogbo awon onilu Ọffa ko lati filu yẹ ọba na si, o lo ko awon onilu wa si Ọffa lati ilu Iragbiji.

## GBAJARE ODO MOBINRIN MEJI

EKO. Awọn odomobinrin meji kekeke ti a fi si ile onise lo sonu lati ojo 20-5-59. ti a si ti nwa wọn kakiri.

Awọn ọdọmọbinrin na to ọmọ ọdun mesan si mẹwa.

Enikẹni ti o ba ri ọmọ aieji nwonyi, ki o lo so fun awon Ọlọpa tabi ki o so fun Ọmọkunrin ni 17, Itolo, Street, Lagos.

# Nigeria Ports Authority

## PORTS ORDINANCE, NO. 27 OF 1954

NIGERIAN PORTS AUTHORITY (ELECTION REGULATIONS 1956)

NOTICE IS HEREBY GIVEN THAT in accordance with the Nigerian Ports Authority (Election Regulations 1956, published as Supplement to Official Gazette No. 31, Volume 43 of 3rd May, 1956) a provisional Ships Dues Register and a provisional Harbour Dues Register containing the names of those persons who are qualified to have their names entered on the respective Registers in accordance with the provisions of paragraph 5 of the Seventh Schedule to the Ports Ordinance 1954 (together with the address of each such person and the number of votes to which he is entitled) have been deposited, together with a copy of the said Regulations, at the Head Office of the Nigerian Ports Authority, 216, Broad Street, Lagos and at the under-mentioned Principal Offices of the Authority in each of the following Ports.

Lagos Accounts Department Marina Offices Marina Lagos.
Dock Superintendent's Office Apapa Quay, Apapa.
Dock Superintendent's Office Customs Quay, Lagos.
Dockyard Manager's Office, Apapa, Dockyard, Apapa.

Port Harcourt... Port Manager's Office, Harbour Rd. Port Harcourt.
Accounts Office, Port Harcourt, Dockyard Manager's Office, Port Harcourt.

Burutu - Custom House Burutu.

Calabar—Harbour Master's Office Calabar.

Degema - Custom House, Degema.

Sapele —Transport Office. Sapele.

Tiko —Custom House, Tiko, Southern Cameroons.

Victoria—Harbour Master's Office, Victoria, Southern Cameroons.

Warri —Harbour Master's Office Warri.

Copies of the provisional Registers may be inspected at any of these offices at all reasonable hours up to and including the 28th day of June, 1959, without payment of a fee.

Persons requiring copies of the said Registers will required to pay the sum of 1s for each register.

Any person qualified to be on either the Ships Due Register or the Habour Dues Register may, by notice in writing stating the nature of his objection delivered to the Secretary of the Authority not later than the 28th day of June, 1959, object to the provisional Register concerned on the ground that his name, qualification or votes are omitted therefrom or incorrectly stated therein or that the name of an unqualified person is included therein, or that the the name, qualification or votes of a qualified person are incorrectly stated therein.

When any person makes objection to any name, qualification or votes entered on one of the Registers, other than his own name, qualification or votes, he shall at the same time as he delivers notice of such objection to the Authority, deliver to the person to whom the entry objected to relates a copy of the notice of objection which he has delivered to the Authority, and without the delivery of such copy of the notice, no such objection shall be valid.

Dated this 26th day of May, 1959.

A. R. CORDON
Secretary to the Authority.

N.P.A. NOTICE. NO.304

## IDAHUN SI IBERE GEORGE KALẸ

Olotu,

Jọwọ gba mi laye lati dahun si ibere ti Ọgbeni George Kalẹ bere ninu iwe irohin Eleti-Ọfẹ, eyiti o jade ni ọjọ kẹta oṣu June 1959 wipe, tani nwon npe ni Gambari.

Idahun ọrọ na niyi; Awon ẹya ara oko kan wa ti awon Hausa npe ni Kemberi, awon ti nwon npe ni orukọ yi jẹ ara oko ti oju won si dudu. Kemberi yi ni Yoruba npe ni Gambari. Ẹru tabi ara oko ni nwon npe ni orukọ na, eyi ni di rẹ ti awon Hausa ki fẹ ki a pe won ni Gambari.

# Lagos Race Club

## CORONATION PRIZE SWEEPTAKES, 1959

The Draw for the above will take place at the Members Enclosure, Race Course on Wednesday, June 17, 1959, at 6.30 p.m.

The Race to be run on Saturday, June 20, 1959. All Tickets should be returned not later than Monday. June 15, 1959.

LATE RETURNS will not be accepted.

ARADAN NERVIGORA

Oogun ẹjẹ pataki fun marale agbara ati arẹmọ pipe fun awọn alaya pupọ O dara fun inarun, ẹjẹ dudu, ṣokun oju, gbigbọn ọwọ, aleun, ailokun ninu ati irufẹ aisan bawọnni. O jẹ ajidewe fun awọn ti agbara wọn ndnku. Ogun yi a gan ni ọkunrin y lo ti o i di "Afẹṣẹ ku bi ojo." 5/6d. pere pẹlu owo ọkọ 1/6d e.g. 7/ Post Free.

**The Egba Trading Aradan Stores 112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street. P O. Box 2. Ebute - Metta. Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.**






RA BUREDI



TI O GBADUN JULỌ TO SI NFUN NI LOKUN-INU ATI ILERA

**BUREDI "DE FACTO"**

TI O

LOKIKI FUN AJẸ GBADUN RẸ.

Printed & Published By The Union Printing And Publishing Company 28, Kosọkọ Street P. O. Box 467 Lagos Phone 23370